EFF'S SURVEILLANCE SELF-DEFENSE

# BÍ A ṢE LÈ: DÈNÀ ÌDOJÚKỌ FÍṢÎÎNÌ

*https://ssd.eff.org/en/about-surveillance-self-defense*

LOCALIZATION LAB

# Bí a ṣe lè: Dènà ìdojúkọ Fíṣîinì

Ìtúnwò Ìkẹyìn
9-6-2017

Nípasẹ̀ ìmúgbòrò ààbò rẹ lórí ayélujára, o lè ṣ'alábààpàdé òṣèré ibi t'ó pète láti sọ ààbò rẹ di yẹpẹrẹ. Òṣèré burúkú ni a pe irú ọ̀tá, tàbí adojúkọni báwọ̀nyí. Bí adojúkọni bá fi ímeèlì tàbí ìsopọ̀ tó jọ gidi, àmọ́ tí ó jẹ́ àrànkàn ni à ń pè ní Fíṣîinì.
Ìdojúkọ Fíṣîinì sábà máa ń rí gẹ́lẹ́ bíi iṣẹ́-ìjẹ́ láti tàn ọ́:

- Kí o ṣíra tẹ ìsopọ̀ adaríẹni s'ójú ìwé mìíì
- Kí o gba ẹ̀da iṣẹ́-àìrídìmú sílẹ̀ sórí ẹ̀rọ-ayárabíàṣáà rẹ; tàbí
- Kí o tẹ orúkọ ìdánimọ̀ àti ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ sórí ibùdó-ìtàkùn tó jọ ògidì.

Ìdojúkọ Fíṣîinì lè tàn ọ́ fi kí o fi ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ sílẹ̀, tàbí tàn ọ́ láti fi iṣẹ́-àìrídìmú àidara sórí ẹ̀rọ̀ rẹ. Adojúkọni lè lo iṣẹ́-àìrídìmú àrànkàn láti fi pàṣẹ fún ẹ̀rọ̀ rẹ, jí ìwífún-un rẹ, tàbí fi ṣe alamí.

Ìtọ́nà yìí yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ láti tètè dá ìdojúkọ Fíṣîinì mọ̀ ní kété tí o bá ṣ'alábààpàdée wọn àti àwọn ọ̀nà tó wúlò tí yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ láti gbaradì fún wọn

# Ìdojúkọ Fíṣîinì tó wà

**Fíṣîinì fún Ọ̀rọ̀-ìfiwọlé (tí a mọ̀ sí kíkórèe ìwé-ẹ̀rí)**

Fíṣîinì fún Ọ̀rọ̀-ìfiwọlé lè tàn ọ́ kí o ṣ'èṣì fún wọn ní ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ nípa fífi ìsopọ̀ ṣ'ọwọ́ sí ọ. Ojúlé ìtàkùn àgbáyé inú iṣẹ́-ìjẹ́ lè darí ẹni sí ibòmíràn. Lórí ẹ̀rọ-ayárabíàṣáà rẹ, o máa rí URL tí ò ń lọ, bí o bá fẹ́ tẹ ìsopọ̀. Ṣùgbọ́n a lè díbọ́n ìsopọ̀ kí o jọ ara, tàbí lílo orúkọ ibùdó ìtàkùn tí ọmọ-ọ̀rọ̀ kan ti dín àti o lè darî rẹ lọ sí ojúùwé ìtàkùn àgbáyé tó jọ èyí tí o ti máa ń lò, bíi Gmail tàbí Dropbox. Àwọn ojú ìwé ìfiwọlé wọ̀nyí sábà máa ń rí bí òótọ́ ti yóò tàn ọ́ láti fi orúkọ-ìdánimọ̀ àti ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ sílẹ̀. Bí o bá ṣe bẹ́ẹ̀, o ó fi ohun-ẹ̀rí ìfiwọléè rẹ ránṣẹ́ sí adojúkọni.

Torí ìdí èyí, kí o tó tẹ ọ̀rọ̀-ìfiwọlé, yẹ pátákó àdírẹ́ẹ̀sì orí ibùdó-ìtàkùn asàwáríkiriì rẹ wò. Yóò fi ògidì orúkọ agbègbè-ìkápá ojú ìwé náà hàn gbangba. Bí kò bá jọ ibùdó tí o mọ̀ tẹ́lẹ̀, máà tẹ̀síwájú! Ṣèrántí wípé àwòrán ilé-iṣẹ́ tí o rí lójú ìwé àyédèrú kò fi hàn wípé ojúlówó ni. Ẹnikẹ́ni lè gbé ẹ̀da àwòrán-ìdánimọ̀ sí orí ojú ìwé tí wọn láti fi tàn ọ́ jẹ.

Àwọn oníṣíṣîinì mìíì máa ń lo ibùdó tó fojú jọ ojúlé-ìtàkùn àgbáyé láti tàn ọ́:
https://wwwpaypal.com/
yàtọ̀ sí,
https://www.paypal.com/. Ẹ̀wẹ̀wẹ̀,
https://www.paypaI.com/ (tí ò ní "i" nílá dípò "L" kékeré yàtọ̀ sí
https://www.paypal.com/. Ọ̀pọ̀ ènìyàn máa ń lo ayí-atọ́ka-ibùdó-ìtàkùn di kúkúrú URL kí URL gígùn ba rọrùn fún kíkà tàbí tẹ̀, ṣùgbọ́n a lè fi èyí ṣe ìpamọ́ ibùdó burúkú. Bí o bá gba URL kúkúrú bíi ìsopọ̀-adáríẹni t.co lórí Twitter, gbìyànjú kí o ṣe àyẹ̀wò ìdánilójú https://www.checkshorturl.com/ láti tú àṣìírí ibi tí ò ń lọ gan-an.

Rántí, ó rọrùn láti ṣe àyédèrú ímeèlì kí ó ba han ojúlé ìdápadà ímeèlì ẹ̀tàn. Èyí túmọ̀ sí wípé ìṣàyẹ̀wò ojúlé ímeèlì àfiṣẹ́-ìjẹ́-ránṣẹ́ kò tó láti mọ̀ bóyá olóòótọ́ ni ẹni tó rí iṣẹ́-ìjẹ́ ránṣẹ́ tàbí ìdà kejì.

**Fíṣîìnì ọkọ̀**

Àwọn fífẹ̀ ni oníífíṣîìnì sábà máa ń lò fi ṣiṣẹ́ láabi wọn. Adojúkọni lè fi ímeèlì ránṣẹ́ sí ọgọọgọ́rùn-ún tàbí ẹgbẹẹgbẹ̀rún ènìyàn láti tẹ àwòrán fídíò alárinrin, ìwé tó ṣe pàtàkì, tàbí àríyànjiyàn ìsanwó kan.

Àmọ́ nígbà mìíràn a máa ń daríi ìdojúkọ fíṣîìnì sí ẹni tí a mọ̀ kiní kan nípa rẹ̀. Èyí ni a pè ní "Fíṣîìnì ọkọ̀." Rò ó wípé o gba ímeèlì kan láti ọ̀dọ̀ ẹ̀gbọ́n Boris tí ó ní àwòrán ọmọọ̀ rẹ̀ nínú. Níwọ̀n ìgbà tí Boris ní ọmọ àti pé ìjẹ́rìí sí ojúlé ímeèlìi rẹ̀ jọ èyí tí o mọ̀ tẹ́lẹ̀, o ṣí i. Nígbà tí o ṣí i, o rí fáìlì àgbàsílẹ̀ kékeré PDF tí a fi mọ́ ọn. Bí o bá ṣí PDF náà, o lè fi àwòrán ọmọ Boris hàn, ṣùgbọ́n o ti ṣe kẹ́lẹ́kẹ́lẹ́ gbé iṣẹ́-àìrídìmú àìdára sórí ẹ̀rọ-ayárabíàṣáà rẹ tí yóò máa ṣe alamí ohun tí o bá ń ṣe wò. Ẹ̀gbọ́n Boris kọ́ ló fi ímeèlì yẹn ránṣẹ́, ṣùgbọ́n ẹni tí o mọ̀ wípé ó ni ẹ̀gbọ́n kan tó ń jẹ́ Boris (tí ó ní ọmọ wẹ́wẹ́). PDF tí o ṣíra tẹ̀, tí aka PDF ń ṣí lọ́wọ́, ni iṣẹ́-àìrídìmú àìdára yìí yá lò fi fọ́n odùu rẹ̀ ká sórí ẹ̀rọọ̀ rẹ. Láfikún sí PDF tí o rí, o ti ṣe àgbàsílẹ̀ ẹ̀da iṣẹ́-àìrídìmú àìdára sórí ẹ̀rọ ayárabíàṣáà rẹ. Iṣẹ́-àìrídìmú àìdára yẹn sì lè jí ẹnimímọ̀ àti ká àwòrán tí ayàwòrán àti gbohùngbohùn rẹ̀ gbọ́ sílẹ̀.

Ọ̀nà tó dára jù fún ìdáààbòbò araà rẹ lọ́wọ́ ìdojúkọ fíṣîìnì ni láti máà tẹ ìsopọ̀ adarí ẹni tàbí ṣí àfimọ́ tí a fi mọ́ ímeèlì. Ṣùgbọ́n àmọ̀ràn yìí kò jẹ́ nǹkankan fún ọ̀pọ̀ ènìyàn. Àwọn ọ̀nà tó yanrantí fún ààbò fíṣîìnì wà nísàlẹ̀.

## Ìdojúkọ Fíṣîìnì tó wà

Rántí, ó rọrùn láti ṣe àyédèrú ímeèlì kí ó ba han ojúlé ìdápadà ímeèlì ẹ̀tàn. Èyí túmọ̀ sí wípé ìṣàyẹ̀wò ojúlé ímeèlì àfiṣẹ́-ìjẹ́-ránṣẹ́ kò tó láti mọ̀ bóyá olóòótọ́ ni ẹni tó rí iṣẹ́-ìjẹ́ ránṣẹ́ tàbí ìdà kejì.

**Fi àfikún fún iṣẹ́-àìrídìmúù rẹ**

Ìdojúkọ Fíṣîìnì alo iṣẹ́-àìrídìmú àìdára sábà máa ń gbójúlé odù-aṣàṣìṣe iṣẹ́-àìrídìmú láti gbé iṣẹ́-àìrídìmú àìdára sóríi ẹ̀rọọ̀ rẹ. Lọ́pọ̀ ìgbà bí a bá ṣ'àkíyèsíi odù-aṣàṣìṣe, oníṣọnà iṣẹ́-àìrídìmú yóò gbé àfikún àtúnṣe jáde. Èyí túmọ̀ sí wípé iṣẹ́-àìrídìmúu ti tẹ́lẹ̀ ní odù-aṣàṣìṣe tó pọ̀ tí a lè lò fi gbé iṣẹ́-àìrídìmú àìdára sórí ẹ̀rọ. Gbígba àfikún iṣẹ́-àìrídìmúù rẹ lóòrèkóòrè yóò dín ewu iṣẹ́-àìrídìmú àìdára kù.

**Lo aṣàkóso ọ̀rọ̀-ìfiwọlé aṣiṣẹ́fúnrarẹ̀**

Aṣàkóso ọ̀rọ̀-ìfiwọlé aṣiṣẹ́fúnrarẹ̀ yóò ṣe àpamọ̀ ibùdó tí o ti ń lo ọ̀rọ̀-ìfiwọlé ọ̀hún. Bí ó ṣe rọrùn fún ènìyàn tó láti bọ́ sí pánpẹ́ ojú ìwé ìfiwọlé ayédèrú, aṣàkóso ọ̀rọ̀-ìfiwọlé ò le è lùgbàdí irú ẹ̀tàn bẹ́ẹ̀. Bí o bá ń lọ aṣàkóso ọ̀rọ̀-ìfiwọlé (títí kan aṣàkóso ọ̀rọ̀-ìfiwọlé tó bá

asàwáríkiriì rẹ́ wà), tí ó kọ̀ láti ṣiṣẹ́ kíkọ ọ̀rọ̀-ìfiwọlé fúnra rẹ̀, ó yẹ kí o ṣe iyèméjì, kí o ṣe àtúnyẹ̀wò ibùdó tí o wà. Síbẹ̀, lo ọ̀rọ̀-ìfiwọlé alágbára tí aṣàkóso ọ̀rọ̀-ìfiwọlé lè kọ fúnra rẹ̀ lórí ojú ìwé ìfiwọlé ayédèrú dípò kí o fi ọwọ́ọ̀ rẹ tẹ̀ ẹ́.

**Jẹ́rìí sí ímeèlì pẹ̀lú afiṣẹ́-ìjẹ́ ránṣẹ́**

Ọ̀nà kan láti mọ̀ bí ímeèlì kan bá jẹ́ ìdojúkọ Fíṣíìnì ni wíwòó ní ìkànnì mìíràn láti yẹ ẹni tó fi ránṣẹ́ wò. Bí ímeèlì náà bá wá láti ilé-ìfowópamọ́ọ̀ rẹ, máà tẹ ìsopọ̀ adarí ẹni sí ojú ìwé mìíràn tí a fi sí inú ímeèlì náà. Kàkà bẹ́ẹ̀, pe ilé-ìfowópamọ́ọ̀ rẹ tàbí kí o ṣí aṣàwáríkiriì rẹ kí o sì tẹ URL ilé-ìfowópamọ́ọ̀ rẹ sí i. Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́, bí ẹ̀gbọ́n Boris bá fi ímeèlì tí o ní àfimọ́ nínú, pè é lórí ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ọ kí o béèrè bóyá ó fi àwòrán ọmọ rẹ̀ ránṣẹ́ kí o tó ó ṣí i.

**Ṣí ìwé afurasí nínú Google Drive**

Àwọn ènìyàn ń fojú sọ́nà fún ìfimọ́ láti ọwọ́ ẹni tí o kò mọ̀. Fún àpẹẹrẹ, oníròyìn sábà máa ń gba ìwé láti ibi pàtàkì oríṣiríṣi. Ṣùgbọ́n ó lè nira láti ṣe ìjẹ́rìísí bóyá ìwé Word, àtẹ́kalẹ̀ Excel, tàbí fáìlì PDF kì í ṣe ti búburú.

Bí èyí bá wáyé, o kò gbọdọ̀ ṣíra tẹ fáìlì tí o gba ẹ̀dàa rẹ̀ sílẹ̀ lẹ́rìnmejì. Kàkà bẹ́ẹ̀, gbé e sóríi Google Drive tàbí akàwé mìíràn lórí ayélujára.
Èyí yóò yí ìwé náà padà sí àwòrán tàbí sí HTML, tí yóò dí gbígbé iṣẹ́-àìrídìmú àìdára lọ́wọ́ lórí ẹ̀rọọ̀ rẹ. Bí ó bá hùn ọ́ láti kọ́ ìmọ̀ iṣẹ́-àìrídìmú tuntun fún kíka ímeèlì tàbí kíka ìwé ilẹ̀ òkèèrè, ó ní ẹ̀rọ ìṣiṣẹ́ tí yóò dín ipa iṣẹ́-àìrídìmú àìdára kù. TAILS jẹ́ ti ẹ̀rọ ìṣiṣẹ́ ti Linux tó máa ń pa araà rẹ̀ rẹ́ lẹ́yìn tí a bá lò ó tán. Qubes jẹ́ ẹ̀rọ ìṣiṣẹ́ mìíràn lórí Linux tí máa ń ṣe jẹ́jẹ́ ya iṣẹ́ s'ọ́tọ̀ọ̀tọ̀ kí wọ́n ba máà di ara wọn lọ́wọ́, tí yóò dín ipa iṣẹ́-àìrídìmú àìdára kù. Méjèèjì ló ń ṣiṣẹ́ lóríi ẹ̀rọ-ayárabíàṣà àgbélétán àti àgbélétábìlì.

O kò le è fi ìsopọ̀ àti fáìlì tí o kò fọkàn tàn sí VirusTotal, iṣẹ́ orí ayélujára ayẹ fáìlì àti ìsopọ̀ wò láti lòdì s'óníróurú agbógunti-odù-àrànká-abẹ̀rọ-ayárabíàṣájẹ́ tí yóò sì jíhìn àbájáde rẹ̀. Èyí kò dájú - antivirus sábà máa ń kùnà láti rí iṣẹ́-àìrídìmú àìdára tuntun tàbí ìdojúkọ - ṣùgbọ́n ó dára ju àìsíi rẹ̀ lọ.

Fáìlìkífáìlì tàbí ìsopọ̀kísopọ̀ tí o bá gbé sórí ibùdó-ìtàkùn-àgbáyé gbogboògbò, bíi VirusTotal tàbí Google Drive, lè jẹ́ wíwò fún ẹnikẹ́ni tó bá ń ṣiṣẹ́ fún ilé-iṣẹ́ yẹn, tàbí ẹnikẹ́ni tó bá ní ààyè sí ibùdó-ìtàkùn yẹn. Bí ìwífún inúu fáìlì náà bá jẹ́ èyí tí ẹnìkejì ò gbọdọ̀ rí, o lè fẹ́ lo òmíràn.

## Ṣọ́ra fún àlàyé inú ímeèlì

Àwọn ímeèlì Fíṣíìnì kan máa ń paró wípé àjọ alátìlẹ́yìn fún ilé iṣẹ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ ni àwọn ń ṣe, wọ́n á sì ní kí o fi ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ ṣọwọ́, tàbí f'ààyè gba "atẹ́rọ̀ ayárabíàṣá ṣe" láti wọ ẹ̀rọ ayárabíàṣàá rẹ, tàbí yọ ààbò orí ẹ̀rọọ̀ rẹ kúrò. Iró nípa ìdí tí ó yẹ kí o fi gbọ́ sí wọn lẹ́nu ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ni ohuninú ímeèlì náà yóò jẹ́, fún àpẹẹrẹ, wípé àpótí ímeèlì rẹ tí kún tàbí wípé olè ti wọ inú ẹ̀rọọ̀ rẹ. Láìbọ́sírere, gbígbọ́ sí àwọn ọ̀daràn wọ̀nyí lẹ́nu lè ṣe àkóbá fún ààbò rẹ.

Ṣọ́ra kí o tó fún ẹnikẹ́ni ní ìwífún tó lè kó ọ síta bí ọmọ ọjọ́ mẹ́ta àyàfi bí ó bá dáa lójú wípé ibi dáadáa ni aṣèbéèrè náà ti wá.

Bí ìfura bá ṣe ọ́ nípa ímeèlì tàbí ìsopọ̀ tí ẹnìkan fi ránṣẹ́ sí ọ, máà ṣí i tàbí ṣíra tẹ̀ ẹ́ àfi ìgbà tí o bá ti gbìyànjú àwọn ìmọ̀ràn tí a kà sókè wọ̀nyí àti bí o bá rí àrídájú wípé kì í ṣe ti aburú.